KILAASI: SS2

ISE: YORUBA

OLUKO: ARABINRIN AYODELE

ISORI ISE: ISE OWO ABINIBI

OSE KEJI

PERIOD (1&2)

## ISE OWO ABINIBI

Ise abinibi je ise ti awon baba nla wa maa n se ti o si je ise asela. O tun je ise ase-file-omo-lowo.  Ise abinibi Yoruba pin si ona merin wonyi:

i. Ise agbe
ii. Ise ode
iii. Ise owo
iv. Ise ona

## ISE AGBE

Ise agbe ni ise to gbajumo julo nile Yoruba. Awon agbe lo n pese ounje fun ara ilu. Yoruba bo won ni ‘ Bebi ba kuro ninu ise , ise buse’. Ise naa ko rorun rara nitori iya ti owo agbe n je lowo oko ati ada.

Orisii agbe meji ni o wa:

i. Agbe alaroje
ii. Agbe aladaa-nla

i. Agbe alaroje ni awon agbe ti n dako fun jije. Iwonba ti won fe je ni won maa n dako re. Won n gbin isu, agbado, egusi, esuru, anamo, ogede, ata ati ewebe lorisirisi.

ii. Agbe aladaa-nla ni awon agbe ti won n fise agbe sise. Oko nla ni won n da lati je ati fun tita. Won tun n toju fun ojo iwaju. Won n gbin koko, agbado,esuru, egusi,opeyinbo, obi, ope, osan ati agbon.

Orisii ile meta lo wa ti awon agbe le dako le:

i. Ile egan: Ile oko tuntun ti won o tii da ri. O maa n ni igi ati igbo nla.Won n gbin koko,ope,kofi, osan ati roba si i.
ii. Ile odan/ile papa: Ile oko ti ko ni igi tabi igbo nla.O dara fun ogbin. A n gbin agbado,egusi,okaa-baba,isu,ege, eree,epa ati opeyinbo si i.
iii. Ile akuro: Ile oko etido ni. A n gbin ireke, ila,efo, agbado,ata ati oronbo sibe.

ISE ODE

Ise ode naa je ise to gbajumo nile Yoruba. Ise ode pin si meta:

1. ODE IGBE: Awon lo n peran nigbo kijikiji, awon eran nla bii kiniun, inaki,ekun ati bee bee lo. Awon ode maa n wo ijakadi pelu eranko nigba miiran, eyi si n seku pa won. Oun ni won se gbodo ni oogun bii egbe, afeeri ati ajabo .
2. ODE ETILE: Awon ni won n se ode oko etile. Won n lo takute,ate, aja, ada, obe ati ibon sakabula lati pa awon eranko ti owo won ka bii okere ati okete.

3. ODE ASODE: Won n so aarin ilu ni ooru nitori awon olosa. Won maa n dira pelu oogun ati ohun elo bii ibon, kumo, ofa, ada ati bee bee lo lati le doju ija ko awon elegiri looru.

## ISE OWO

Awon ise-owo to gbajumo laaarin awon Yoruba ni aso hihun, epo fifo, ilu lilu,aro dida, isegun, eni hihun ati bee bee lo.

1. ASO HIHUN: Laaarin awon eeyan agbegebe Oyo , ise abinibi won ni aso ofi, kijipa ati aso-oke hihun. Owu ibile ni won fi n hunso. Won maa n pa owu funfun laro awo ti o ba wu won ki won to hun un sugbon lode oni, orisiirisii awo ni won le ri ra, o si n muse won rorun.
   Lara awon ohun elo aso hihun ni apasa, owu, keke -owu, pangolo adi ati bee bee lo.
2. ENI HIHUN: Lagbegbe Ejigbo, Ilesa ni Ipinle Osun ati Ekiti ni ise eni hihun ti gbajumo laye atijo. Tokunrin tobinrin lo n hun eni. Lara awon eni ti won n hun ni pakiti ati eni ore .
   Awon ohun elo eni hihun ni paiko, obe, aro ati iko.
3. ARO DIDA: Kaakiri ile Yoruba ni won ti n sise aro dida. Awon obinrin lo n se e, won si gbodo ni imo kikun nipa aro dida ati batani lorisiirisii ni yiya. Awon ohun elo aro dida ni ikoko nla, omi, aro, orogun gigun,iko ati ohun elo iyaworan. Won n dara lorisiirisii sara aso.

PERIOD(3)

ISE ONA

Awon ise ona to gbajumo laarin awon Yoruba ni ise agbede, ise gbenagbena, ikoko mimo, igba fifin, irun didi ,ise gbajamo ati bee bee lo.

1. ISE AGBEDE: Iran Irenimogun lo ni ise agbede. Awon alagbede ni won ro ada, oko, obe, aake ati ibon ti awon agbe ati ode fi n dako tabi sise ode.
   Lara awon irinse agbede ni owu, iponrin, ewiri, ikoko omi, omo-owu, gbinrin ati emu.
   Orisii agbede meta lo wa. Awon ni:
   i. Agbede ogun: Awon ni won n fi irin ro oko, ada aake ati akoro.
   ii. Agbede ide,baba ati oje: Awon n ro ado ide, opa orisa, oruka, egba-owo ati ese ati edan ogboni .
   iii. Alagbede: Awon lo n ro goolu owo ati yeti.

2. ISE GBENAGBENA: Awon lo n fi igi gbe tabi dara si ara igi.Iran Abogunde lo n gbe igi fun oba.
   Ohun elo won ni igi Iroko( fun ere gbigbe), ada, igi awun( fun ere gbigbe), igi oganwo( fun odo gbigbe) ati osese obe .

3. ISE EPO-FIFO:Iran Aresa lo ni ise yii. Awonokunrin lo n ko eyin lati ori igi ope ti awon obinrin si n fo epo ni eku. Ohun elo epo fifo ni igba ope, ikoko nla, eyin, koroba, abo, apere, gorodoomu nla ati omi.

4. ISE GBAJAMO: Ise okunrin ni.Won n gerun tabi farun ori fun okunrin. Lara ohun elo won ni abe ifari, iyarun,omi ose, abefele,ati aloomu.

5. Irun didi: Onidiri ni a n pe awon to n sise yii. Bataani oniruuru ni won le di. Won tun n fi owu ati roba ko irun. Lara ohunelo won ni ilarun, adi-agbon, apoti/ ijokoo ati owu/ roba.

ISORI ISE: LETA GBEFE ATI AIGBAGBEFE

OSE KETA

PERIOD(1,2 & 3)

LETA GBEFE

Leta gbefe ni leta ti a n ko si awon ti a mo ri. A n ko leta yii si obi, ore ati awon miiran ti o sunmo

wa. Gege bi oruko re, leta yii faye gba ki a se efe tabi ki eeyan.

AWON IGBESE KIKO LETA GBEFE ABUDA LETA GBEFE

i. Adiresi akoleta ati deeti ni apa otun oke iwe
ii. Ikini ibere/ ikini akoko
iii. Ara/ koko leta
iv. Ikini ipari
v. Oruko akoleta

APEERE KIKO LETA GBEFE

2, NIDB Estate Eruwen,

Ikorodu,

Ipinle Eko,

Naijiria.

Ojo keje osu Igbe, odun 2020.

Ronkus,

Bawo ni ore mi, se alaafia ni o wa ni? Oko re ati awon omo re nko ni Jamani?

______________________________________________

______________________________________________

______________________________________________

Emi ni tire nitooto,

Ebunoluwa.

## LETA AIGBAGBEFE

Leta aigbagbefe ni leta ti a n ko si awon ti a ko mo ri, paapaa julo awon ti o wa ni ipo ase. Iru leta

yii ni a n ko nigba ti a ba n wase. A le ko o si awon wonyi:

i. Oga ileewe
ii. Olotuu iwe iroyin
iii. Ajo WAEC, NECO, PHCN
iv. Ileewe giga tabi Yunifasiti
v. Gomina / alaga ijoba ibile ati bee bee lo.

## AWON IGBESE KIKO LETA AIGBAGBEFE / ABUDA LETA AIGBAGBEFE

i. Adiresi akoleta ati deeti ni apa otun oke iwe
ii. Adiresi / ipo eni ti an ko leta si ni apa osi, labe deeti

iii. Ikini ibere/ ikini akoko
iv. Akole/ ori-oro leta
v. Ara/ koko leta
vi. Ikini ipari
vii. Oruko akoleta ni kikun

APEERE KIKO LETA AIGBAGBEFE

2, NIDB Estate Eruwen,

Ikorodu,

Ipinle Eko,

Naijiria.

Ojo keje osu Igbe,odun 2020.

Oga ileewe,

Strong Tower Academy,

Obafemi Awolo Way,

Oke Ota-Ona,

Ikorodu.

Oga,

ITORO AYE LATI MA WA SI IBI ISE

Mo ni ki n fi to yin leti wi pe aisan iba n yo mi lenu, N o si nilo aye lati lo toju ara mi ni ile-iwosan.

Tiyin tooto,

Ayodele Ebunoluwa.

ISORI ISE: ETO EBI

OSE KERIN

PERIOD(1,2& 3)

ETO EBI

Ebi n toka si baba, iya, egbon, awon omo ati ibatan. Inu agboole ni eto ebi ti bere.

Baale ni olori agboole. Oye idile si ni oye Baale. Kii se oun ni okunrin ti o dagba julo ni agboole sugbon awon agba ninu ebi yan an nitori iriri ati ogbon re.

Ninu eto ebi ti Baale n dari, Iyaale ile, Obinrin ile ati Omo ile lo nise ti won n se lati le mu ki agboole dun un gbe. Yoruba bo won ni " Bi oode odun, bi igbe nilu n ri".

OJUSE BAALE

1. Aawo pipari: Ojuse re ni lati ri i wi pe alaafia joba ni agboole. Bi aawo tabi ede aiyede ba wa laaarin awon eeyan, ojuse re ni lati yanju re. Yoruba bo won ni “Agba kii wa loja, ki ori omo tuntun wo”.
2. Alejo gbigba: Baale ni o ni ase lati gba alejo wo inu agboole. Bi molebi kankan ba fe gba alejo ti yoo sun, Baale gbodo mo si i.
3. Lile alejo kuro ni agboole: Bi alejo ba se ohun ti ko ye ni agboole, Baale ni ase lati le e kuro ninu agboole.
4. Adari eto ayeye ebi: Baale lo n dari eto ayeye bii igbeyawo, isomoloruko ati bee bee lo. nrin ile yooku nigba ti won ba Odede Baale ni won ti n wure nigba ayeye bakan naa. Oun ni won n fun ni itan eran ti won ba pa nibi ayeye.
5. Imojuto omoole: Baale gbodo mo ijade ati iwole awon omokunrin ati omobinrin ninu agboole.
6. Asoju ebi nibi ipade adugbo tabi ilu: Oun ni o maa n soju agboole nibi ipade adugbo . Oun ni oba ilu n ranse si bi enikeni ba se asemase ninu agboole.

OJUSE IYAALE ILE

Iyaale ile ni iyawo akofe Baale. O le ma je oun ni o dagba julo ni ojo-ori sugbon o gbodo je oun ni iyawo ti Baale koko fe. Ojuse re ni iwonyi:

1. Aawo pipari: O maa n pelu Baale nigba ti won ba n yanju aawo laaarin awon orogun lori ipo agba tabi laaarin awon omo ile.
2. Olori ati asoju awon obinrin ile: Oun lo n saaju awon obinrin ile yooku nigba ti won ba ni ode ebi ka. Oun naa lo n gba iyawo tuntun wole.

3. Iya agbebi: Oun ni o n toju aboyun bakan naa lo n gbebi nigba ti asiko ibimo ba to. Oun naa lo n toju iya ati ikoko.
4. Olutoju asa ati ise ebi: Oun ni o ni imo kikun nipa itan idile, oriki orile-ile oko. O ma n ko awon iyawo tuntun ni ohun ti o ye.

## OJUSE OBINRIN ILE

1. Itoju ile ati ayika: Won n gba ile ile ati ayika.
2. Ina dida: Won n dana jije mimu, paapaa julo lasiko odun ibile tabi ayeye miiran.
3. Mimu ayeye larinrin: Awon ni n je ki ariya ebi dun ki o si larinrin nipa kikorin ati jijo.
4. Itoju iyawo tuntun ati ikoko: Won n toju iyawo to sese wole, aboyun ile, iya ati omo ikoko.
5. Gbigbasa laruge: Awon lo n gbe asa yo nibi ayeye bii igbeyawo ati isinku agba. Won tun n ko awon omoole.

## OJUSE OMOOLE

1. Ise ebi ati ti ilu ni sise: Awon okunrin ile lo n sise oko riro, ona yiye, ile oku gbigbe, oku sinsin ati bee bee lo. Awon omo ile lobinrin n sise bii aso fifo , ina dida ati bee bee lo.
2. Eran pipa nibi ayeye: Ise awon okunrin ile ni lati pa eran nigba odun ibile ati ibi oku ana.Won letoo si apa eran ti won ba pa.
3. Iranwo ni igbejo Baale: Won n wa nibi ti Baale ti n gbejo lati maa teti sile ko ohun to n sele.